17. Ki ẹ si mu aṣibori ìgbàlà, ati idà Ẹmí, ti i ṣe ọ̀rọ̀ Ọlọrun: (Isa 59:17; Heb 4:12; 1 Tess 5:8.)

18. Pẹlu gbogbo adura ati ẹ̀bẹ̀ ni ki ẹ maa gbadura nigba gbogbo ninu Ẹmí, ki ẹ si maa ṣọra si i ninu iduroṣinṣin gbogbo, ati ẹ̀bẹ̀ fun gbogbo eniyan-mímọ́: (Matt 26:41; Luk 18:1; Filp 1:4.)

19. Ati fun mi, ki a lè fi ohùn fun mi ki emi lè maa fi ìgbóyà ya ẹnu mi, lati maa fi ohun ijinlẹ ihinrere hàn, (A.A. 4:29; 2 Kor 3:12.)

20. Nitori eyi ti emi jẹ ikọ̀ ninu ẹ̀wọ̀n: ki emi lè maa fi ìgbóyà sọ̀rọ̀ ninu rẹ̀, gẹgẹ bi o ti tọ́ fun mi lati maa sọ. (2 Kor 5:20; Filp 1:20.)

**Ọ̀rọ̀ asọpari.**

21. Ṣugbọn ki ẹyin pẹlu lè mọ̀ bi nkan ti ri fun mi, bi mo ti nṣe si, Tikiku, arakunrin olufẹ ati iranṣẹ olootọ ninu Oluwa, yoo sọ ohun gbogbo di mímọ̀ fun yin: (A.A. 20:4.)

22. Ẹni ti mo rán si yin nitori èyí naa, ki ẹ lè mọ̀ bi a ti wà, ki oun lè tu ọkàn yín ninu.

23. Alaafia fun awọn ará, ati ifẹ pẹlu igbagbọ, lati ọdọ Ọlọrun Baba wa, ati Oluwa wa Jesu Kristi. (1 Pet 5:14; Gal 5:6.)

24. Ki oore-ọ̀fẹ́ wà pẹlu gbogbo awọn ti o fẹ Oluwa wa Jesu Kristi ni àìṣẹ̀tàn.

50

# AWỌN ARA FILIPPI

**(A.D. 64)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ Ìkíni.**

PAULU ati Timoteu, awọn iranṣẹ Jesu Kristi, sí gbogbo awon eniyan-mímọ́ ninu Kristi Jesu ti o wà ni Filippi, pẹlu *awọn biṣọbu ati awọn diakoni: (2 Kor 1:1; A.A. 16:1; 1 Kor 1:2.)

2. Oore-ọ̀fẹ́ si yin, ati alaafia, lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun Baba wá, ati Oluwa Jesu Kristi. (1 Pet. 1:2.)

**Ọpẹ́ ati Adura Fun Ijọ Filippi.**

3. Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun mi ninu gbogbo iranti yin ti mo nṣe, (1 Kor 1:4.)

4. Nigbagbogbo ninu gbogbo adura mi fun yin ni emi nfi ayọ̀ bẹ̀bẹ̀, (Rom. 1:9.)

5. Nitori ìdàpọ̀ yin ninu ihinrere lati ọjọ kinni wá titi fi di isinsinyìí. (A.A. 2:42; Rom 12:13.)

6. Ohun kan yìí saa dá mi loju pe, ẹni ti o ti bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ rere ninu yin, yoo ṣe àṣepé rẹ̀ titi fi di ọjọ Jesu Kristi: (ẹsẹ 10.)

7. Gẹgẹ bi o ti tọ́ fun mi lati ro eyi nipa gbogbo yin, nitori ti mo fi yin sọ́kàn mi, niwọn bi o ti jẹ pe gbogbo yin ni alábapin oore-ọ̀fẹ́ mi ninu ìdè mi, ati ninu ìdáhùn-ẹjọ mi, ati ifẹsẹ̀múlẹ̀ ihinrere. (2Pet1:13; 2Kor7:3; ẹsẹ13-17)

8. Nitori Ọlọrun ni ẹlẹri mi, bi mo ti nṣafẹri yin to gidigidi ninu ìyọ́nú Jesu Kristi. (Rom 1:9; Gal 1:20.)

9. Eyi sì ni mo ngbadura fún pé, ki ìfẹ́ yin lè maa pọ̀ si i siwaju ati siwaju ninu ìmọ̀ ati ìmòye gbogbo. (1 Tess 3:12; Kol 1:9.)

10. Ki ẹyin lè dán ohun ti o dara yàtọ̀ wò; ki ẹ si jasi olododo ati alaijẹ-ohun-ìkọ̀sẹ̀ titi fi di ọjọ Jesu Kristi:

11. Lẹhin ìgbà ti ẹ ti kún fun eso

(1) *Awọn biṣọbu ati awọn diakoni, tumọsi, Awọn alabojuto ati awọn iranṣẹ ti o nran awọn alabojuto lọwọ ninu ijọ; (wo Tit 1:5–9; 1 Tim 3:1–13.)

ododo lati ọdọ Jesu Kristi, fun ogo ati ìyìn Ọlọrun.

**Ìrírí Paulu ninu iṣẹ – ìránṣẹ.**

12. Njẹ emi fẹ ki ẹyin mọ, ará, pe nkan wọnyìí ti o dé bá mi, o kúkú yọrí si ilọsiwaju ìhìnrere;

13. To bẹẹ ti o ti di mímọ̀ laarin awọn ọmọ-ogun aafin ati gbogbo awọn ẹlomiran pé ìdè mi ninu tubu jẹ fun Kristi. (Filp 4:22.)

14. Ati pe ọpọlọpọ awọn arakunrin ni o ti ni igbẹkẹle ninu Oluwa nitori ìdè mi, wọn si nfi ìgboyà gidigidi sọ̀rọ̀ Ọlọrun láìbẹ̀rù. (ẹsẹ 7.)

15. Nitootọ awọn ẹlomiran tilẹ nfi ìjà ati ilara waasu Kristi; awọn ẹlomiran si nfi inu rere ṣe e. (Filp 2:3.)

16. Awọn ti ikẹ́hìn nfi ifẹ ṣe e, nitori ti wọn mọ̀ pe a o gbe mi dide fun ìgbèjà ihinrere, (1 Kor 9:17; ẹsẹ 12.)

17. Ṣugbọn awọn ti iṣaaju ẹ̀wẹ̀ nfi ìjà waasu Kristi, ki i ṣe pẹlu ootọ́ inú, wọn ngbèrò lati fi ipọnju kún ìdè mi ni. (Filp 2:3.).

18. Njẹ kinni? Bikoṣepe nibi gbogbo, ibaa ṣe ninu ìfẹ̀tànṣe ni, tabi ninu otitọ́, a sá nwaasu Kristi; emi si nyọ̀ nitori naa.

19. Nitootọ́, emi o si maa yọ̀ nitori ti mo mọ̀ pe eyi ni yoo yọrí si ìgbàlà fun mi lati inu adura yin wá, ati ififkun Ẹmí Jesu Kristi, (2 Kor 1:11.)

20. Gẹgẹ bi o ti jẹ ìfojúsọ́nà gidigidi ati ireti mi pe ki oju máṣe tì mí ninu ohunkohun, ṣugbọn pe pẹlu ìgboyà gbogbo, bi nigbagbogbo, bẹẹ ni nisinsinyìí a o gbe Kristi ga lara mi, ibaa ṣe nipa ìyè, tabi nipa ikú. (Rom 8:19; 5:5; Ef 6:19.)

21. Nitori, niti emi, lati wa láàyè jẹ́ Kristi, lati kú jẹ èrè.

22. Ṣugbọn bí lati wà láàyè ninu ara bá jẹ eso iṣẹ́ mi, nigba naa ohun ti emi o yàn, èmi kò mọ̀.

23. Ṣugbọn emi nbẹ ni iye-meji mo ni ifẹ lati lọ ati lati wà lọdọ Kristi; nitori o dara pupọ jù: (2 Kor 5:8; 2 Tim 4:6.)

24. Sibẹ lati wa ninu ara jẹ́ anfani nitori ti yín.

25. Bi eyi si ti dá mi loju, mo mọ̀ pe emi o duro, emi o si maa ba gbogbo yin gbé fun ilọsiwaju ati ayọ̀ yin ninu igbagbọ;

26. Ki ìṣògo yin ninu mi baa lè di pupọ gidigidi ninu Jesu Kristi nitori ìpadàbọ̀ mi sọdọ yín. (2 Kor 5:12;2 Tim 4:6.)

27. Kìkì pe ki ẹ saa jẹ ki iwa-ayé yin maa rí gẹgẹ bi ihinrere Kristi; pe yálà bi mo tilẹ̀ wá wò yin, tabi bi emi kò sí, ki emi lè maa gburo bi ẹ ti nṣe, pé ẹyin duro ṣinṣin ninu Ẹmi kan, ẹyin jumọ njìjàkadì nitori igbagbọ ihinrere, pẹlu ọkàn kan;

28. Ki ẹ má si jẹ ki awọn ọ̀tá dẹruba yin lohunkohun. Eyi ni o jẹ́ àmì ti o dájú fun iparun wọn, ṣugbọn ti ìgbàlà yin, ati eyiyìí lati ọwọ́ Ọlọrun wá. (2 Tess 1:5; Rom 8:17.)

29. Nitori niti Kristi, ẹyin ni a ti yọnda fun, ki i ṣe lati gbàgbọ́ nikan, ṣugbọn lati jìyà nitori rẹ̀ pẹlu; (Matt 5:12; A.A. 16:19.)

30. Nipa níní ìjàkadì kannaa tí ẹyin ti rí, ti ẹ si gbọ nisinsinyìí pe o jẹ́ temì.

ORI 2.

**Jesu ni àwòṣe wa.**

NITORI naa bi ìtùnú kan bá wà ninu Kristi, bi ìṣìpẹ̀ ifẹ kan bá sì wà, bi ìdàpọ̀ ti Ẹmi kan bá wà, bi ìyọ́nú-àanú ati iṣeun bá wà, (2 Kor 13:14; Kol 3:12.)

2. Ẹ mu ayọ̀ mi kún, ki ẹyin lè jẹ́ oninu kannaa, ninu ìfẹ́ kannaa, ninu iṣọ̀kan, ati ni inú kannaa. (Jhn 3:29; Rom 12:16; 1 Pet 3:8.)

3. Ẹ máṣe fi ìjà tabi ogo asán ṣe ohunkohun: ṣugbọn ni ìrẹ̀lẹ̀ ọkàn ki olukuluku ro awọn ẹlomiran si ẹni ti o sàn ju oun tikara-oun lọ. (Gal 5:26; Rom 12:10; 1 Pet 5:5.)

4. Ki olukuluku yin máṣe wo ohun ti ara rẹ̀, ṣugbọn olukuluku ohun ti ẹlomiran. (Rom 15:1,2.)

5. Ẹ ní èrò yìí ninu yin eyi ti o ti wà

pęlu ninu Kristi Jesu: (Matt 11:29; 1 Pet 2:21.)

6. Ęni ti, bi o tilę ję ìrísí Ọlọrun, kò kà á si ohun ti iba fi ìwọra gbámú lati ba Ọlọrun dógba. (Jhn 1:1; 2 Kor 4:4; Jhn 5:18.)

7. Ṣugbọn o bọ́ ogo rę̀ silę̀, o si mu àwọ̀ iranṣę́, a si ṣe e ni aworan eniyan. (Jhn 1:14; Gal 4:4; Heb 2:17.)

8. Nigba ti a sì ti ri i ni ìrí eniyan, o rę ara rę̀ silę̀, o si tęriba titi di ojú ikú, ani ikú orí àgbélèbú. (Matt 26:39; Jhn 10:18; Heb 5:8.)

9. Nitori naa, Ọlọrun pęlu si ti gbe e ga gidigidi, o si ti fi orukọ kan fun un ti o borí gbogbo orukọ: (A.A. 2:33; Heb 2:9; Ef 1:20,21.)

10. Pé ni orukọ Jesu ni kí gbogbo eekún maa kúnlę̀, awọn ęni ti nbę ni ọ̀run, ati awọn ęni ti nbę lori ilę̀, ati awọn ęni ti nbę nisàlę̀ ilę̀; (Matt 28:18; A.A. 2:36.)

11. Ati pe ki gbogbo ahọ́n maa ję́wọ́ pe, Jesu Kristi ni Oluwa, fun ogo Ọlọrun Baba. (Jhn 13:13; A.A. 2:36.)

**Ohun ti o ję ọ̀ranyàn fun awọn Onigbagbọ.**

12. Nitori naa ęyin olufę mi, gęgę bi ęyin ti ngbọran nigbagbogbo, kii ṣe nigba ti mo wà lọdọ yin nikan, ṣugbọn paapa nisinsinyìí ti emi kò si, ę maa ṣiṣę ìgbàlà yin yọri pęlu ìbẹ̀rù ati ìwárìrì, (Filp 1:5; Ef 6:5.)

13. Nitori pe Ọlọrun ni o nṣiṣę ninu yin, lati fę ati lati ṣiṣę fun ìfę́ inu rere rę̀. (2 Kor 3:5.)

14. Ę maa ṣe ohungbogbo láìsí ìkùnsínú ati ìjiyàn. (1 Kor. 10:10; Rom 14:1.)

15. Ki ęyin lè ję́ alailę́gàn ati oníwà tútù, ọmọ Ọlọrun, aláìlábàwọ́n, laarin oniwa wíwọ́ ati alárekérekè orilę-èdè, laarin awọn ęni ti a nri yin bi ìmọ́lę̀ ni ayé, (Matt 5:45; Ef 5:1; 5:8.)

16. Ki ę si maa di ọ̀rọ̀ ìyè mú gírígírí; ki emi lè ṣogo ni ọjọ́ Kristi pe emi kò sáre lásán, bęę ni emi kò sì ṣe làálàá lásán. (2 Kor 1:14; 1 Tess 2:19.)

17. Àní, bi a tilę ndà mí bi ọtí-ìrubọ sori ębọ iṣę-ìsìn igbagbọ yin, mo yọ̀, mo si nba gbogbo yin yọ̀ pęlu. (2 Tim 4:6; Rom 15:16; Kol 1:24.)

18. Bakannaa ni ki ęyin maa yọ̀, ki ę si maa bá mi yọ̀ pęlu.

**Timoteu ati Epafroditu nbọ̀ wá.**

19. Ṣugbọn mo ni ireti ninu Jesu Oluwa, lati rán Timoteu si yin ni lọọlọọ yìí, ki emi pęlu lè ni ìfàyàbalę̀ nigba ti mo ba gburo yín. (Rom 16:21.)

20. Nitori emi kò ni ęni oninu kannaa ti o dabi rę̀, ti yoo maa fi tinútinú ṣe aniyan yin (1 Kor 16:10.)

21. Nitori gbogbo wọn ni o ntọju nkan ti ara wọn, ki i ṣe awọn nkan ti Jesu Kristi. (1 Kor 10:24; 13:5.)

22. Ṣugbọn ęyin ti mọ ọn dajudaju pé, gęgę bi ọmọ lọdọ baba rę̀, bęę ni o sì ti nbá mi ṣiṣę́ pọ̀ ninu ihinrere. (1 Kor 4:17; 1 Tim 1:2.)

23. Nitori naa oun ni mo ni ìrètí lati rán si yin nisinsinyìí nigba ti mo bá wòye bi yoo ti ri fun mi.

24. Ṣugbọn mo gbę́kèle Oluwa, pe emi tikarami pęlu yoo wá ni lọ́ọlọ́ọ.

25. Mo ka a si pe nkò lè ṣairán Epafroditu arakunrin mi si yin, ati olubaṣiṣę́ mi, ati ọmọ-ogun ęlęgbę́ mi, iranşę yin pęlu, ti ę rán lati ṣeránṣę́ fun mi ninu àìní mi. (Filp 4:18; Film 2.)

26. Nitori ti ọkàn rę̀ fà si gbogbo yín, o si kún fún ibanuję, nitori ti ęyin gbọ́ pé o ṣe àìsàn. (Filp 1:8.)

27. Nitootọ́ ni o ti ṣe àìsàn títí de ojú ikú: ṣugbọn Ọlọrun ti ṣaanu fún un; kìí si i ṣe fun oun nikan, ṣugbọn fun mi pęlu, ki emi máṣe ni ibanuję lori ibanuję.

28. Nitori naa ni mo ṣe ni itara lati rán an, pe nigba ti ęyin ba sì tún ri i, ki ęyin lè yọ̀ ati ki ibanuję mi le dínkù.

29. Nitori naa ę fi ayọ̀ pupọ gba a nipa ti Oluwa; ki ę si maa bu ọlá fun irú awọn ęni bęę: (1 Kor 16:18; 1 Tim 5:17.)

30. Nitori pé nitori iṣę́ Kristi ni o ṣe súnmọ́ ęnu-ọ̀nà ikú, ti kò si ka ęmí ara rę̀ sí, lati mu àìtó iṣę́ ìsìn yin sí mi kún.

ORI 3.

**Apẹẹrẹ Paulu.**

NI àkótán, ará, ẹ maa yọ̀ ninu Oluwa, Ki i ṣe inira fun mi lati kọwe ohun kannaa si yin, ṣugbọn fun yin o jẹ àìléwu. (Filp 4:4.)

2. Ẹ kiyesara lọdọ awọn ajá, ẹ kiyesara lọdọ awọn oniṣẹ-buburu, ẹ sì kiyesara lọdọ awọn onílà. (Gal 5:15; 2 Kor 11:13.)

3. Nitori awa ni onílà, ti nsin Ọlọrun nipa ti Ẹmí, awa si nṣogo ninu Kristi Jesu, awa kò sì ní igbẹkẹle ninu ẹran-ara; (Rom 2:28,29; Gal 6:14,15.)

4. Bi emi tikarami pẹlu ti ni igbẹkẹle ninu ara. Bi ẹnikẹni ba rò pé oun ni ìgbẹ́kẹ̀lé ninu ara, temi tilẹ pọ̀:

5. Ẹni ti a kọ nila ni ijọ́ kẹjọ, lati inú kukute Israẹli wá, lati inu ẹ̀yà Bẹnjamini, Heberu lati inu Heberu wa; niti ofin, Farisi ni emi; (Rom 11:1; 2 Kor 11:22.)

6. Niti ìtara, emi nṣe inunibini si ijọ; niti òdodo ti o wà ninu ofin, mo jẹ aláìlẹ́gàn. (A.A. 22:3; Rom 10:5; Luk 14:33.)

7. Ṣugbọn ohunkohun ti o ti jásí èrè fun mi, awọn ni mo ti kà si òfo nitori Kristi. (Matt 13:44; Luk 14:33.)

8. Nitootọ laiṣe àní-àní mo sì ka ohun gbogbo si òfo nitori itayọ ìmọ̀ Kristi Jesu Oluwa mi: nitori ẹni ti mo ti ṣòfò ohun gbogbo, mo si kà wọn si ìgbé, ki emi lè jèrè Kristi, (Ef 4:13; 2 Pet 1:3.)

9. Ki a si lè bá mi ninu rẹ̀, laini ododo ti emi tikarami, ti o ti inú òfin wá, ṣugbọn èyí ti o ti inú ìgbàgbọ́ wà ninu Kristi, ododo lati ọdọ Ọlọrun nipasẹ ìgbàgbọ́: (Rom 10:5; 9:30.)

10. Ki emi lè mọ ọn, ati agbára ajinde rẹ̀, ati lati jẹ́ alábápín ninu ìyà rẹ̀ nigba ti mo ba faramọ ọn ninu ikú rẹ̀; (Rom 6:3–5; 8:17.)

11. Bi o lè ṣeeṣe ki emi lè ni ajinde kuro ninu òkú. (A.A. 26:7.)

12. Ki i ṣe pe ọwọ́ mi ti tẹ́ẹ́ ná, tabi mo ti di pípé: ṣugbọn emi nlepa ǹṣó, bi ọwọ́ mi yoo lè tẹ èrè naa nitori eyi ti a ti dì mí mu pẹlu, lati ọ̀dọ̀ Kristi Jesu wá. (1 Tim 6:12; 1 Kor 3:10; A.A. 9:5,6.)

13. Ará, emi kò ka ara mi si ẹni ti ọwọ rẹ̀ ti tẹ ẹ ná: Ṣugbọn ohun kan yìí ni emi nṣe, emi ngbàgbé awọn nkan ti o wà lẹ́hìn, mo si nnọ̀gà wo awọn nkan ti o wà niwaju. (Luk 9:62; 1 Kor 9:24.)

14. Emi nlépa lati dé òpin aré-ìje naa fun èrè ìpè giga Ọlọrun ninu Kristi Jesu. (Heb 6:1; 2 Tim 1:9.)

15. Nitori naa, ẹ jẹ́ ki awa ti a dàgbà nipa ti ẹmi ni èrò yìí; bi ẹyin ba sì ni èrò miran ninu ohunkohun, eyi naa pẹlu ni Ọlọrun yoo fi hàn yín. (1 Kor 2:6; Gal 6:16; Gal 5:10.)

16. Kìkì pe, ibi ti a ti dé ná, ẹ jẹ ki a maa rin ni ojú ọ̀nà kannaa, ki a ni èrò kannaa.

**Ìkìlọ̀ nipa awọn ẹlẹkọ-òdì.**

17. Ará, ẹ jumọ ṣe afarawe mi, ẹ ṣe akiyesi awọn ti nrin bẹẹ, àní bi ẹ ti ní wa fun àpẹẹrẹ (1 Kor 4:16; 1 Pet 5:3.)

18. Nitori ọpọlọpọ ni nrìn, nipasẹ awọn ẹni ti mo ti nwi fun yin nigbakugba, àní, ti mo si nsọkún bi mo ti nwi fun yin nisinsinyìí, pe, ọ̀tá agbelebu Kristi ni wọ́n: (A.A. 20:31; Gal 6:14.)

19. Ìgbẹ̀hìn wọn ni iparun, ikùn wọn sì ni ọlọrun wọn, wọn sì nṣògo ninu ìtìjú wọn, awọn ẹni ti ntọju ohun ti ayé. (2 Kor 11:15; Rom 16:18; 6:21; 8:5,6; Luk 16:15–24.)

20. Nitori ìlú-ìbílẹ̀ wa nbẹ lọ́run: lati ibi ti awa pẹlu gbe nfojusọna fun Olugbala, Jesu Kristi Oluwa: (Ef 2:19; Kol 3:1; 1 Kor 1:7.)

21. Ẹni ti yoo sọ ara ìrẹ̀lẹ̀ wa di ọ̀tun ki o lè bá ara ogo rẹ̀ mu, nipa agbara ti ó mu ki o ṣeeṣe fun un lati tẹ orí ohun gbogbo ba fun ara rẹ̀. (1 Kor 15:43; Kol 3:4; Ef 1:19.)

ORI 4.

**Paulu parí Ọ̀rọ̀ ìyànjú rẹ̀.**

NITORI naa ẹyin ara mi olufẹ, ti mo si nṣàfẹ́rí gidigidi, ayọ̀ ati adé mi, ẹ duro ṣinṣin bẹẹ ninu Oluwa, ẹyin

olufẹ mi. (Filp 1:8; 1 Kor 16:13; Filp 1:27.)

2. Emi nbẹ Euodia, mo si nbẹ Sintike, ki wọn ni inú kannaa ninu Oluwa. (Filp 2:2.)

3. Mo sì bẹ̀ ọ́ pẹlu, bi alájọrù àjàgà mi tootọ́, ran awọn obinrin wọnyìí lọ́wọ́, nitori wọn bá mi ṣiṣẹ pọ̀ ni ìfẹ̀gbẹ́-kẹ̀gbẹ́ ninu ihinrere, ati Klẹmẹnti pẹlu, ati awọn olubaṣiṣẹ mi iyoku pẹlu, orukọ awọn ti nbẹ ninu ìwé ìyè. (Rom 16:3; Luk 10:20; Ifh 3:5.)

4. Ẹ maa yọ̀ ninu Oluwa nigbagbogbo: mo si tun wí. Ẹ maa yọ̀. (Rom 12:12; Filp 3:1.)

5. Ẹ jẹ́ ki ipamọra yin di mímọ̀ fun gbogbo eniyan, Oluwa nbẹ nitòsí. (Heb 10:37; Jms 5:8,9.)

6. Ẹ maṣé ṣe aniyan ohunkohun; ṣugbọn ninu ohun gbogbo, nipa adura ati ẹ̀bẹ̀ pẹlu idupẹ, ẹ maa fi ìbéèrè yin hàn fun Ọlọrun. (Matt 6:25; Ef 6:18.)

7. Ati alaafia Ọlọrun, ti o ju ìmòye gbogbo lọ, yoo ṣọ́ ọkàn ati èrò yin ninu Kristi Jesu. (Jhn 14:27; Kol 3:15; 1 Pet 1:5.)

8. Ni akotan, ará, ohunkohun ti i ṣe òótọ́, ohunkohun ti i ṣe ọ̀wọ̀, ohunkohun tii ṣe títọ́ ohunkohun ti i ṣe mímọ́, ohunkohun ti i ṣe fífẹ́, ohunkohun ti o ni ìròhìn rere; bi iwa títọ́ kan bá wà, bi ìyìn kan bá sì wà, ẹ maa gba nkan wọnyìí rò. (1 Pet 2:12; 1 Tess 5:22.)

9. Awọn nkan, ti ẹyin ti kọ́, ti ẹyin si ti gbà, ti ẹnyin si ti gbọ́, tí ẹyin si ti ri lọwọ mi, ẹ maa ṣe wọn: Ọlọrun alaafia yoo si wà pẹlu yín. (Filp 3:17; Rom 15:33.)

**Paulu fi ìfẹ́ hàn si ọrẹ awọn ara Filippi.**

10. Emi yọ̀ gidigidi ninu Oluwa pé, nisinsinyìí, ẹyin tún ti sọjí ninu àníyàn ọkàn yin si mi, nitootọ ọkàn yin nfà mọ́ mi ṣugbọn ẹnyin kò ni ànfàní tó.

11. Kii ṣe pe emi nsọ nitori àìní: nitori pé ipòkípò ti mo bá wà, mo ti kọ́ lati ni itẹlọrun ninu rẹ̀. (1 Tim 6:6.)

12. Mo mọ̀ bi a ti ṣe nrẹ ara silẹ̀, mo si mọ̀ bi a ti ṣe ndi pupọ: ni ohunkohun ati ni ohun gbogbo mo ti kọ́ aṣiri lati maa jẹ àjẹyó ati lati wà ni àìjẹ, lati maa ni àníto ati lati ṣe alaini. (1 Kor 4:11; 2 Kor 11:9.)

13. Emi le ṣe ohun gbogbo ninu Kristi ẹni ti nfi agbara fun mi. (Jhn 15:5; 2 Kor 12:9 )

14. Ṣugbọn ẹyin ṣeun gidigidi niti pé ẹyin ṣe alabapin ninu ipọnju mi. (Filp 1:7.)

15. Ẹyin paapaa si mọ̀ pẹlu, ẹyin ara Filippi, pé ni ìbẹ̀rẹ̀ ihinrere, nigba ti mo kuro ni Makedonia, kò sí Ijọ kan ti o ba mi nṣe alabapin niti gbígbà ati fifunni, bikoṣe ẹyin nikanṣoṣo. (2 Kor 11:8,9.)

16. Nitori ni Tessalonika ẹyin fi nkan ranṣẹ, lẹẹkinni ati lẹẹkeji fun àìní mi (A.A. 17:1; 1 Tess 2:9.)

17. Kii ṣe nitori ti emi nfẹ ẹ̀bùn naa: ṣugbọn emi nfẹ èso ti yoo maa di pupọ nitori yín.

18. Ṣugbọn mo ni ohun gbogbo, mo sì ti di pupọ̀: mo si kún nigba ti mo ti gba nkan wọnyìí lọwọ Epafroditu ti a ti rán wa lati ọ̀dọ̀ yin, ọrẹ oloorun dídùn, ẹbọ ìtẹ́wọ́gbà, tii ṣe inu didun gidigidi si Ọlọrun. (Filp 2:25; 2 Kor 2:14.)

19. Ṣugbọn Ọlọrun mi yoo pèsè ni kíkún fun gbogbo àìní yín, gẹgẹ bi ọrọ̀ rẹ̀ ninu ogo ninu Kristi Jesu. (Psm 23:1; 2 Kor 9:8; Ef 1:7.)

20. Ṣugbọn ògo ni fun Ọlọrun ati Baba wa lae ati laelae. Amin. (Gal 1:4; Rom 11:36.)

**Ọ̀rọ̀ Asọpari.**

21. Ẹ ki olukuluku eniyan-mímọ́ ninu Kristi Jesu. Awọn ará ti o wà pẹlu mi ki yin.

22. Gbogbo awọn eniyan-mímọ́ ki yin,paapaa awọn ti nṣe ti agbo-ile Kesari.

23. Oore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa wa, ki o wà pẹlu ẹ̀mí yin. Amin.